# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI OGOGBO LAWA

No. 752, FRIDAY, JULY 24, 1964 (2D)


## Ọgbọn Ọkọ Oju ọmi Ri Si Agbami!

KALABA:— Gbogbo a ọn enia ti nwọn wa ninu ọkọ oju-omi bẹrẹsi mi bi igbati alupupu to bajẹ fẹ gun ori oke nigbati atẹgun (yi) lile kan bẹrẹsi ja ninu odo Kalaba, ti ọgbọn ọkọ oju omi si dojude ni oju omi ni alẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa pe awọn ọkọ oju omi na wa ni oju omi, awon enia inu oko na si npa ẹja loju omi ni asiko ti atẹgun na nja ni.

Nigbati atẹgun lile na bẹrẹ, lẹsẹkẹsẹ ni awọn apẹja na ti akiyesi pe, ọjọ na kọ dara ni nwọn ba nsare gbe ọkọ oju omi wọn lọ si Ebute ṣugbọn nigbati nwọn o fi de Ebute, ọgbọn ninu awọn ọkọ na lo dojude sinu odo

Irohin awọn Ọlọpa tun ṣi alaye pe bi gbọ o awọn ero Ebute ti nwọn wa ra ẹja ti ri ohun ti o ṣẹlẹ ni nwọn fi wa sọ fun awọn ni Tesan. Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa si de ti lati wa yọ awọn enia medọgbọn

Ṣugbọn oku enia medọgbọn ninu ọgọrun enia ni awọn Ọlọpa ti ri gbe jade ni isalẹ odo. Nwọn si ti ri tun nwa awọn yoku lowọ, ṣugbọn nwọn ko ti ri oku wọn. Bi nwọn ba ti ri wọn ẹ o tun ma a

# AWỌN OLORI OṢIṢẸ JARE ẸJỌ

EBUTE MẸTTA:- Asẹhinwa asẹhinbọ ile ẹjọ kekere ti Ebute Mẹta da awọn olori oṣiṣẹ mẹta ninu awọn marun ti Ijọba ba nṣe ẹjọ pe awọn Olori oṣiṣẹ lu ofin pe ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe ipade ode gbangba tabi ki nwọn ma to kakiri ode gbangba eyiti nwọn ni awọn Olori Oṣiṣẹ na ati awọn oṣiṣẹ ṣe ni ọgbọnjọ osu karun ọdun 1964



Ọgbẹni Mich. Imoudu

Awọn Olori oṣiṣẹ ti Ijọba fi ẹsun na kan ni Alhaji Haruna Popoọla Adebọla, Ọgbẹni Michael Imoudu, Ọgbẹni Ok o n g i w i, Nnaemeka Chukunrah ati John Alabi.

Ninu awọn ti adajọ da lare pe ki nwọn ma lọ pẹlu alafia ni Alhaji Haruna Popoọla Adebọla, Ọgbẹni Michael Imoudu ati ọgbẹni Wahabi Goodluck. Adajọ ile ẹjọ na sọ ninu rẹ nigbati o da awọn mẹta silẹ ti oni ki nwọn ma lọ pẹlu alafia ni Adajọ na sọ pe on yio ṣ ẹjọ ti awọn Olori oṣiṣẹ meji yoku Oni lọ tọ ni awọn oṣiṣẹ meji ti adajọ ko ti gbọ ẹjọ wọn ni ọgbẹni Nnaemeka Chukuwurah ati John Alabi.

Ẹni to ṣe ẹkẹfa ninu awọn Olori oṣiṣẹ ti ile ẹjọ ba nṣe ẹjọ ni ile ẹjọ ti Ebute Mẹtta ni Ọgbẹni Nuru Tiamiyu Cole eyiti o o ku si ile iwosan fun ara to fi pa laseko igbati awọn oṣiṣẹ bẹrẹ rogbodiyan na.

Ẹsun ti Ijọba fi kan awọn Olori oṣiṣẹ na na ni pe nwọn nṣe ipa de iwọde gbangba lati Ebute-Mẹtta e y i t i awọn Olori oṣiṣẹ na ati awọn oṣiṣẹ bẹrẹsi wọde lati Ebute-Mẹtta titi de ori kereni ni Iddo awọn Ọlọpa to bẹrẹsi tu awọn oṣiṣẹ ati olori wọn ka eyiti o da ija silẹ larin awọn oṣiṣẹ pẹlu awọn Ọlọpa ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọgbọnjọ oṣu karun ọdun yi.

Ọpọlọpọ awọn oṣiṣẹ lo si fara gbọgbẹ na ọjọ ti rogbodiyan ni bẹ silẹ eyiti nwọn fi gbe ọkan ninu olori



Ọgbẹni W. Goodluck

awọn oṣiṣẹ na Alhaji Haruna Adebọla lọ si ile iwosan ti Igbobi lati lọ ṣe itọju rọ.

Ninu awọn to tun fi ara gbogbẹ na ni Ọgbẹni Nuru Tiamuju Cole eyiti nwọn tete gbe lọ si ile iwosan ko to di pe Ọgbẹni Nuru ku si ile iwosan na.

Lẹhin ti Ijọba fi ẹsun kan awọn Olori Oṣiṣẹ yi ni Ọjọ keji ti rogbodiyan na ṣẹlẹ ni Ọjọ Iṣẹgun ti iṣe Ọjọ ko kan le logbọn Oṣu karun Ọdun yi.

Nigbati o di ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kẹrin Oṣu kẹfa Ọdun yi ni awọn Oṣiṣẹ jakejado orile de ilẹ Naijiria taku pe awọn ki yio ṣiṣẹ aya fi ti Ijọba ba gbe abayọri ẹkunwo Owo Oṣu eyi ti oluwadi Morgan ṣe ki awọn to le bere iṣẹ.

Rogbodiyan si bẹrẹ jakejado ilẹ Naijiria eyiti o ji jẹ pe ilu Eko fi ilu nrunfun gbogbo gọtọ ti awọn osiṣẹ ko silẹ lati sọ mọ.

Nigbati rogbodiyan pe awọn osiṣẹ na iṣẹ si-



Alhaji H. P. Adebọla

lẹ fẹ daogua silẹ kakiri-ari ile iṣẹ ni orilẹ ede ilẹ Naijiria ni a w ọ n Ọlọpa ṣọja mura lati le jẹki alafia wa kakiri Naijiria.

Ọpọlọpọ ilu jakejado ilẹ Naijiria ni ko ri ina tan ti nwọn ko tun ri omi mu to fi jẹpe pe awọn ọlọpa ati ṣọja ti ilẹ Naijiria lo nṣe iṣẹ to yẹ ki awọn oṣiṣẹ sẹ titi de ile iṣẹ ifi iwe ranṣẹ si ilu okere.

Ọpọlọpọ ile iṣẹ ọkẹ aimọye pọhun nu laisẹku ti awọn oṣisẹ taku pe awọn koni si ṣẹ laljẹ pe awọn abayọri ẹku nwo owo-osu eyiti igbimọ oluwadi Margan se.

Nigbati awọn Ijọba ilẹ Nigeria ripe gbogbo nkan ko rigbọ mọ ni nwọn tete fito si pẹlu awọn olori oṣisẹ na Eyiti awọn oṣisẹ pada sẹnu iṣẹ ni ọjọ osu kẹfa ọdun yi.



Aworan Oke yi ni ti igbati awọn Ọlọpa fi kondo nwọn dara si awọn Oṣiṣẹ lara nigbati gbogbo awọn Oṣiṣẹ nto bọ wa si Eko lati Ebute - Metta

# IWE SI OLOTU

## Ere Were Ni Ere Ẹyọ

Dakun Alagba, Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le fun mi ni aye yi lati fi kin Ọgbẹni Mallam Ilẹhin ọrọ ti o sọ sinu iwe yin ni ọjọ kini oṣu keje ọdun yi nipa pe ki a pa ere ẹyọ tire



AGOGORO ẸYỌ

Mo fi ara mọ ohun ti Mallam yi wi, ti a ba fi oju inu wo, ao ri pe ọpọlọpọ enia ni o fi ara ṣeṣe ni ọjọ Ẹyọ, nitori ina kuna ti awọn ẹyọ na ma nna enia bio-tilẹjẹ pe o ṣifila tabi gele ati bata rẹ, nwọn ko tilẹ ni bikita ti nwọn ba ti le pade Oluwarẹ, inakuna ni nwọn yio na,

Bi o ba ṣe pe bi ti atijọ ni nwọn nṣe ni o dara ti enia ko ba ti de fila tabi wọ bata ẹyọ ki na enia, bi o ba si mọ ọ ri diẹ ni yio rọra na ọ, ṣugbọn ti awọn isinyi kọ, ina bakaya ni wọn na enia ni idi eyi ni mo ṣe fi ara mọ pe ki a pa ere ẹyọ rẹ

Emi ni,
R. S. K, Kogbẹbẹ
EKO.

## Enyin Ọmọ Ogbomọshọ E Ronu

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ lati ba awọn ọmọ ilu Ogbomọshọ to wa ni ile ati ni idalẹ sọrọ ijinlẹ ati eyi ti yio ṣe gbogbo wa ni anfani.

Gbogbo wa lo ti mọ gẹgẹbi okan ṣe nlọ si ni ilẹ Yoruba bayi ati pe a si ti wẹ o ni gbigbọ a ati olotu a si ti mọ eyi ti o ba wa lara mun niau rẹ

Nitori eyi a si ti mọ iru Ijọba ti yio ba wa lara jọ ati pe lati igba ti rogbodiyan ti wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ko si anfani kan ti a ri ni ilu wa a ẹtan jẹ ti awọn ẹgbẹ oṣelu kan ntan wa jẹ ati pe mo fe ki yẹ ẹnyin enia mi pe asiko Idibo si ti nsunmọ bayi ki a si mọ iru ẹgbẹ Oṣelu ti yio ṣe rere fun wa lẹhin idibo na ati ẹ ki a si mọ iru enia ti a o dibo fun ni asiko na.

Nitori eyi ko si ẹgbẹ kan ju ẹgbẹ ọlọpẹ lọ ni ilẹ Yoruba to tun le ṣe anfani fun wa ẹ jẹ ki a ronu ki a si fi ọkanrọkan dibo fun ẹgbẹ ọlọpẹ.

Emi ni
Adigun Ola
Ogbomoshọ

## Ẹ Ku Ewu Ọjọ'Bi

Mba sọpẹ bi Olotu Iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye lati ki Oloye Festus Okotie-Eboh, Alaṣẹ eto inawo Ijọba Apapọ ku ewu ọjọ'bi eyiti o ṣe laipẹyi, mo gbọ pe Oloye na di ẹni ọdun mejileladọta (52 years)

Ọjọ a dale o, Oluwa yio tun bọ ma ṣe amọna rẹ ninu iṣẹ rẹ, alafia ati ẹmi gigun Oluwa yio tun bọ fun ọ o.

Emi Ajẹgborodagba ko tete gbọ ni, nko ba ti fo de Mid-West Iphun lati wa fi ete ko resi pẹlu ọti ẹyẹ o, ṣugbọn nko ni ṣe alai gba nkan ọjọ'bi ti emi na owo yin o sa, ẹ ma reti mi ni ọfisi yin loni.

Mo ki yin ẹ ku ewu ojo'bi o aṣeyi ṣe amodun o,

Emi ni,
Ajẹgboro Dagba,

EKO

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




Bi amodi "IKỌ" ti ọlọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lenu on akan bi ọdun kan tabi ju bẹ lo awọn egbogi rọ irọbi fun le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun Iko otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, Ikọ iili, Ikọ ti o mọ mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungsa tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba ti ṣan Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri i wa to ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jeun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pelu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisirisi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square, Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ojalta Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba
ATI NI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişiriş, Iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Oun wa wo lẹẹkan ṣoṣo ko si ri iyatọ

# Agbabiaka Di Orişa

Lati Ọwọ Alhadji Y. A. Disu

A ma a ngbọ ọ lati igbati alaiye ti da aiye pe, "Enia kukuru bilisi" Ọrọ yi si wa titi di oni-oloni ko si şe ko danu ki işe gbogbo awọn enia ti o ba kuru ni nwọn jẹ eşu tabi bilisi enia.

Şugbọn laisi aniani. Ọpọlọpọ awọn enia kukuru gbandi ni nwọn jẹ bilisi enia, nwọn yara pupọ ju Nwọn si ni agidi ju Gbogbo ohun ti o ba si ti ni ju ninu ki i dara mọ O ti bajẹ niyẹn Idi niyi o, ti nwọn fi nsọ pe "Enia kukuru bilisi" Şugbọn mo fẹ ki ẹnyin Onkawe mi yi mọ daju daju daada pe diẹ ninu awọn enia kukuru mbẹ ti nwọn yaayi ni gbogbo ọna Nwọn korira wa ijamba, iwa aboo si iwa sọndi-sọndi, iwa tirumi ni-maa-şe, ti nwọn si fẹran lati ma a şe işẹ ododo pupọ Ọlọla Ologbe Y. Bamzaf Adisa Subair kuru Şugbọn o korira gbogbo iwa abocsi ati iwa ijamba O fẹran işẹ ododo pupọ O si şe Ọmọ enia pupọ On ni aropodogiri ati ipilẹşẹ ile itọju Owo "NATIONAL BANK OF NAIJIRIA"

Ni igba-aiye rẹ, ko gba awọn enia laye lati ma a ya owo aya-tunya ko gba enia laye lati ma a ya owo ẹsilu Laakaye rẹ pe pupọ Ologbe H. Adisa Şubair Ọrun işe o.

Enia kukuru ni Oloba Aminu Kosọkọ Ọmọ Ọyọ Eko ni Inu rẹ si dara pupa si t'aja ti ẹran. Ki hu iwa abosi ati bilisi.

Ọpọlọpọ awọn enia gigun saugbandan ni nwọn yaayi ni gbogbo ọna Ni nwọn fẹran işẹ ododo. Igbesi aiye wọn si dun ju oyin lọ.

Nşe ni awọn si maa nfi gbadun şe ayọ Fun afẹẹrẹ, do gọ enia ti Oloye Abudu Salami Agbabiaka. Mo bẹru, mo si fila o. Rọbirọbi enia ni gbogbo igun mẹrẹrin,

Naijiria ni ko mọ ọ o gba jumọ ju iş na ẹlẹẹta lọ. O ş itọju işẹ Ọlọpa daada tobẹ gẹẹ ti ofi de aye „Ọga mo bẹri sa!" ti o s tun fi de ipo adajọ ododo. O si di Orişa,

Sugbọn diẹ ninu awọn doogo enia mbẹ ti o fẹran iwa ẹgan, ẹgan ko si ni ki

WO OJU EWE KẸFA

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Ọjọ oni ko buru tobẹ şugbọn ọrọ nla kan yio şẹlẹ lori lori ohun kan Maşe gbẹkẹle alejo rara Maşi şe ba ẹnikẹni jowu papọ

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Ere nbẹ fun ọ lati jẹ şugbọn agbara rẹ ko bẹ şe suru, ki oma si şe aşeju kio le dara fun ọ

ARIES (Mar 21 - April 19) Fi oju ati ọkan rẹ si awọn nkan tio nşe pataki nikan, ki o si ma feti si gbọran kio to fesi si ọrọ, şugbọn jẹki ọgbọn ori pe daradara

TAURUS (April 20 - May 20) Ire nbẹ fun ọ loni ayọ ati adun ni igbẹhin rẹ Iwọ yi otitọ ọrọ gbọ lati ọdọ awọn enia p taki feti si imọran ẹwọn

GEMINI (May 2 - June 20) A ẹ yio mu ọ loni sugbọn opara fun kio mase baenia sọrọ pupọ sọra rẹ ki ori rẹ ma ba Ẹsọ di ọwọ rẹ

CACEN (June 21-July 20) Awọnọrẹ rẹ atijọ ati awọn titun yio nilọtẹrun siọ awọn obinrin yio s fẹ lọplọọ ọrẹ atijọ yio s nkan iyanu si ọ

LEO (July 32 - Aug 22) Gbogbo ariski rẹ dabi eyiti o tilọ sibẹ bo tilẹ jẹ pe igba ko lọ bi orere fun ọ ko sai si okuta idugbolu loju ọpa rẹ maşe gbẹkẹle ẹnikan tabi alejo

VIRGO (Aug 23 e Sept 23) Odara kio tete wa wọrọ kọ fi se ada masi se kọ ohun tio ma da bẹ ni kio mase atako si ọrọ ẹnikan ki wọn ma mu ọ ni ọta

LILORA Sept 24 - Oct 23:- ọkan rẹ koni balẹ loni kio ma si şe jẹki ibinu bori ọgan ko şe alaisi iṣoro diẹ ọgbọn ori rẹ ko si to sugbọn iwọ yio gbọ irohin ayọ

SCORPIO Oct 22 - Nov22 Ire bẹ fun ọ lọiọ loni kole şe yio maşe si işubu ati idi e fun nipa owu jij gbo gbo rẹ yio ma şişọ pọ tun rere

SAGITTARIUS 23 - Dec 21:- Iṣọrọ kan pẹlu igbo ara kan yio şẹlẹ lori iwọ pelu ẹnikan ninu awọn ẹbi rẹ mura lati şe atunşe

CAPRICORN (Dec 22 - Ja 19) Awọn ọrẹ rẹ atijọ ati awọn titun yio jẹri ọjọ oni suwọn fun ọ kio si gba imọran nipa bi aşe ntọju owo nipa işẹ.


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patroise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Granantee Neat Work And Quick Service

## Modupẹ Printing Press

16, Bamgbose Street
Phone 21985, Lagos.

## I. C. M. Tọniki (100 Tablets)



Gbiyanju lati ma lo I. C. M. TỌNIKI nigbagbogbo I. C. M. TỌNIKI o wa fun Ọkunrin, Obinrin ati Alaboyun pẹlu, I. C. M. Tọniki o dara fun aini ẹjẹ to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun ẹjẹ şe daradara. Bere fun ẹyọ igo kan, tabi dọsini. odidi Apo (50 dozes) wa pẹlu. Iler. i ogun ọrọ o Bere lọwọ Elegbogi oyinbo ti o wa ni adugbo rẹ fun I. C. M. TỌNIKI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si Ọdọ:—
MOSỌBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Street, LAGOS.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA

## "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişẹşẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" n gbakugba yio salọ pẹlu igoaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju Bere Egbogi na ni Şọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos.
Phone: 22878 Naijiria, (Ọja Ita Faji)

# Lati Oju Ewe Keji

**Oloye Awolọwọ: Bẹ kọ gbo gbo ọrọ rẹ irọ ni patapata Adedipẹ:- Bẹni ika yio ka onika**

Oloye Awolọwọ tun dahun ibere kan eyiti o sọ pe ti ọgbọn ori enia ba pe ko ni sọ pe on yio gbero lati jẹ ile to jẹ pe o l ›bara gidigidi ati pe iru enia b: yio mọ p agbara on yio dinku

Oloye Awolọwọ sọpe on ko ran Dokita Ọladipo Maja lọ si ọdọ Nkruma lati gba ohun ọsẹ ati pe gbogbo ọrọ ti Maja sọ pe irọ ni gbogbo rẹ patapata.



Ọgbẹni Latifu Jakande

Nigbati nwọn tun bere lọwọ Oloye Awolọwọ pe nje o gbero lati da rogbodiyan ati lati dite si Ijọba apapọ nigbati o sọ ni ile Igbimọ aşofin ti apapọ Ijọba Naijiria ni ọjọ kọkandinlọgbọn oşu karun 1962 nigbati o sọ pe ilẹ Naijiria si ti yi pada

Oloye Awolọwọ si dahun



Ọgbẹni Omişade

pe ohun ti ọrọ na jẹmọ ko ba pe nwọn doju Ijọba Naijiria bolẹ ati pe fun gẹgẹbi ijọba ilẹ Naijiria gbe ofin pajawiri kalẹ ni ipinlẹ Iwọ orun Naijiria ati ọrọ na Oloye Awolọwọ



Ọlọla Ade. Ademọla

sọ pe ki şe on lo sọ ọrọ iru bẹ pe Oloye Enahoro lo sọ ninu ipade ile igbimọ Aşofin ti apapọ Ijọba Naijiria

Adedipẹ : Ero ọkan rẹ ni lati di Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria?

Oloye Awolọwọ :- Bẹni ero ọkan mi ni pe emi yio di Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria.



Ọgbẹni Ọlawọyin

Adedipẹ : o ni ero na lokan lati ọjọ kẹdogun oşu ekejila ọdun 1959 ki ilẹ Naijiria to gba ominira.

Oloye Awolọwọ: E o mi ni lati di Alakoso kini apapọ Ijọba Naijiria lati ọjọ kẹdogun oşu kẹta ọdun 1959

Adedipẹ Ero rẹ lati di Alakoso Ijọba apapọ bọ si ọjọ lẹh n abayọri eto idibo ti ile igbimọ aşofin ti apapọ Ijọba ni ọdun 1959

Oloye Awolọwọ : Ero mi lati di Alakoso Ijọba apapọ ko ti ja so fo gẹgẹbi mo şe joko si nu apoti ẹ'ẹri yi mo ni ireti pe emi yio di Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria


# Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ Etutu ... ... lati e bo ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku ... oko lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohun toba si dawọ rẹle ni yio ja şi rere awọn baba awọn ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mi
Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko şe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe ayi lọwọ şaşa arun ni o ko ni le wo ko si ni ijaya pe arun tabi mimu. ọ a si ka le pa ọ Iye owo 25/-
e larin Ẹyọ.. Ajẹ- ti o ba nfin turari yi ba a ti şe şure rẹ Ajẹ ati abatẹnijẹ ko ni foju si ọ lara ohun ọohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwe ko mọ alta ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo ki siwa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pa golo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| ...we Gbedegbẹyọ Hausa | 3/ |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Aml Ara | 3/-3 |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọşẹ Işẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| ati agbara Psalm ẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Ara | 30/- |

# APEJUWE ILE IŞẸ WA

Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson. bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ti ile itawe wa wa. Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja niadirẹsi mi niyi:—

Akiyesi Pataki:- ale ri awọn iwe wọn yi ra ni garage Iddo, Mushin, Ikorodu road ati gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba ri i ra wa si ọdọ mi ngo ta fun.

**J. O. Shoyinka**

c/o Postal Agent,
1, Isiba Street
Itirẹ Via,
Suru Lere. Yaba

# UROLYSAN DRAGES'

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney-Bladder) fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu. ẹhin didun Ibadi Gige tabi riro, eri ile itọ, tabi tọ-jijo enisitọ rirun, rukuruku. Pipọn, aikoleri itọ lati tọ to, lakuregbe, orunkun ọwọ, ẹsẹ, Ejika wiwu tabi riro



Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati orişirişi awọn aisan tabi amodi, ba wọn. yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹlo si ni ilu Naijiria nitorina şọra ki awọn eleru tabi awọn ori rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ, maşe gba rara! Owo rẹ jẹ Sile mẹfa abọ 6/6d owo Ọkọ Silə kan abọ (1/6d)

Bere Egbogi yi ni şọbu awọn:-

NIGERIA MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHNE 20278
Waterloo Medcine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AJYE TENI GBOGBO LAWA

No. 752, FRIDAY JULY 24. 1964 (2D)

## Ęgbę N. P. C. Abęokuta Sọ Pe Nwon O Fę Ajumoşepọ Egbę Dęmọ

ABĘOKUTA:- Awọn ọmọ Ęgbę N P. C ti ęka Abęękuta ti sọ ninu ọrọ wọn pe ko si nkan ti wọn ni pọ pęlu awọn ọmọ Ęgbę kan ti nwon pe ara wọn ni Southern Peoples' Party nipa ọrọ ti awọn ọmọ Ęgbę na sọ pe awọn ko fę ajumọsepọ Egbę Dęmọ NNDP eyiti Oloye S L Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlę Iwọ Orun Naijiria nşe olori.

Awọn ọmọ Ęgbę na fi ęnu sọkan ninu ipade Ęgbę na ti nwọn şe ni ilu Abęokuta laipę yi.

Awọn ọmọ Ęgbę N. P. C. tun sọ nin u ọrọ wọn pe awọn ko lodi si orukọ Ęgb ę na ti nwọn yi pada ni ipinlę n sugbọn awọn ko şa ję ba awọn ọmọ Ęgbę Dęmọ şepọ lonakọna,

Ninu ọrọ ti Olori Ęgbę na sọ ni Abęokuta ni pe ero lati ba awọn ọmọ Ęgbę NNDP pa pọ yio mu iparun wa fun Ęgbę N, P. C. ni Naijiria.

Awọn ọmọ Ęgbę na bu ęnu ętę lu Alakoso kekere ni ile işę Alakoso apapọ Ijọba Naijiria ọgbęni Samuel Lana ati Alhaji K O S Arę ti nwọn ję Alakoso Ęgbę na ni Ipinlę Iwọ orun nipa pe ti ara wọn nikan ni nwọn njadu lati le ni igbega

Awọn ọmọ ęgbę ni kesi Olori ęgbę N P C ati Alakoso Ijọba Ipinlę Ariwa Naijiria Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello Sardauna ti ilu Sokoto lati le tete da si ọrọ na ki akoko idibo si ile igbimọ aşofin ti apapọ Ijọba ilę Naijiria

# Ęgbę Afęnifęre Sọ Pe :

# Ę TU ILE IGBIMỌ IJỌBA IPINLĘ IWỌ ORUN KA

Ninu ọrọ ti o jade lęnu akọwọ Alakoso ęgbę Afęnifęre Ọgbęni S. Ade Şowęmimọ ni bi ipade kan ti awọn ọmọ ęgbę na şe laipę yi ni awọn ọmọ ęgbę sọ pe o ti han gbangba pe ęgbę Dęmọ ko le tę awọn enia ilę Yo uba l'ọrun ati gęgębi awọn ęgbę kan to ti parę eyiti orukọ ęgbę to ti pa rę na nję U. P. P.

Awọn ọmọ ęgbę na sọ pe ohun to le tę awọn enia ipinlę Iwọ orun lọrun nipe ki nwọn tu ile igbimọ Ijọba Ipinlę Iwọ Orun ka bayi ati l: ję ki awọn enia ipinlę na yan Ijọba ti yio tę wọn l'ọrun eyiti yio mu Ilọsiwaju awọn Ọmọ Yoruba wa.

Awọn Ọmọ ęgbę Afęnifęre tun sọ pe ko si nkan kan ti ęgbę Dęmọ N. N, D, P, şę lati gba ti nwọn ti nşe akoso ipinlę na ati pe dipo ki Ilọsiwaju wa nşe ni awọn Ọmọ ęgbę Dęmọ nfi agbara mu awọn enia ti ko ba şę ti nwọn ati pe ki nwọn fi iya maje awọn enia ti ko ba şę ęgbę wọn Awọn Ọmọ ęgbę na tun sọ pe Ọpọlọpọ ile ękọ ni awọn ęgbe Dęmọ yio fi agbara wọn sọ pe ki nwọn ti pa tabi ki nwọn da awọn Ọmọ ile ękọ na duro ni ile ękọ eyiti awọn obi awọn Ọmọ na ti sanwo ile wọn silę ti awọn Ọmọ na ko le kọ iwe mọ.

Awọn ọmọ ęgbę na tun sọ pe dipo ki awọn Ọba ti nwọn ję baba fun gbogbo Ipinlę na le ma gbadun nşe ni awọn ęgbę Dęmọ tun nşe owo oşu wọn di kọ bọ (1d) kan şoşo l'ọdun. Awọn ọmọ ęgbę na sọ pe iru iwa bayi ko le fa eto Ijọba rere wa si Ipinlę Iwọ Orun bikoşe pe ki nwọn tu ile Igbimọ Aşofin Ipinlę na ka iati le fi eto Ijọba rere lelę.

Awọn ọmọ ęgbę na tun fi ęnu kan ere ọmọ ilę Yoruba kan ti a npe ni Ogunde eyiti awọn Ijọba ęgbę Dęmọ ti Ipinlę Iwọ Orun fi agbara buburu wọn da duro lati ma şe işę o jọ rę ni Ipinlę na eyiti ọmọ ilę Yoruba ni lati mọ daju pe iwa Ikorira ni awọn ęgbę nlọ ni ipinlę na ati pe ohun ti o daju lati şe ni pe ki nwọn tu ile igbimọ na ka lati le yan Ijọba ti yio tę awọn enia lọrun.

Awọn ọmọ ęgbę Afęnifęre tun fęnu kan nipa iwa ikorira ti awọn ọmọ ęgbę Dęmọ tun nhu ni ipinlę Iwọ na eyiti nwọn fi nda ọpọlọpọ awọn Olukọ tabi oşişę ti ko ba ti şe ęgbę won duro.

Awọn ọmọ ęgbę na tun sọ pe ęrọ asọrọmagbesi ti Ijọba ipinlę Iwọ Orun si ti di nkan ti awọn ọmọ ęgbę na fi npolowo ęgbę ati pe ọpọlọpọ owo to yę nwọn fi tun ipinlę na şe o si ti di nkan ti awọn ęgbę Dęmọ nlo fun nkan ti aru wọn nikan.

Awọn ęgbę na tun rọ gbogbo awọn ọmọ Yoruba lati mọ pe ęgbę Dęmọ ko si fę ilọsiwaju awọn enia ipinlę na bi ko şe pe iparun ilę Yoruba ni nwọn nfę.

Awọn ọmọ ęgbę afęnifęre tun sọ ninu ọrọ wọn pe ni asiko akoso Ijọba lowọ ęgbę Dęmọ pe ko si ilọsiwaju kankan ati pe awọn gba ęgbę 'Dęmọ ti nşę akoso Ijọba ipinlę Iwọ orun gęgę bi ọta awọn ọmọ ilę Yoruba ati pi pa julọ fun Iparun ti nwọn nwa fun ọmọ enia ipinlę na tabi lati le gbe awọn enia ipinlę na ta fun emi orin eyiti awọn ęgbę Afęnifęre si ka awọn enia iru bę gęgębi ọta si eto ilọsiwaju ati Ijọba rere fun orilę, ede Naijiria.

Awọn ọmọ ęgbe na si kere awọn ęgbọ Dęmọ(NNDP) ti nfi agbara se Ijọba lati tete ri ọkan şe ki wọn tete jęki awọn enia ipinlę na le tete dibo ki wọn le yan Ijọba ti yio ba wọn lara mu ni ipinlę na ati eyiti yio mu eto Ijọba rere fęsę mulę Ni ipinlę iwọ orun Nigeria Ni ipari awọn ọmọ ęgbę na sọpe awọn ni igbękęle olori ęgbę na Oloye Awolọwọ ati Ade le olori ęgbę Alhaji D S Adegbenro

The best watch in its class




Full range of Oris watches available from:

S. A. AJIBỌLA & SONS
279, L E D B Shops,
Imman Ligali Street,
Akauni Area,
LAGOS

## Agbabiaka Di Orişa

Lati Ọwọ Alhadji Y. A. Disu

oyin ma dun. Ti o ri iwa ijamba, iwa tęmbęlękun ati iwa kenimani. E o wa ri i pe, şę işę awamaridi ni işę Edumare. Ni akoko kan baba doogo kan mbę, o ya ọlę to işo, o si fęran lati maa fi awada şe agbe. Nigbati o si bosi aye Mọgaji Ogun baba rę ti o tęsi on ati ọwọn aburo rę ti awọn Ologbe ęgbọn rę ko si ję bajętan ni o ni ki awọn ti o pọwọ le on dasta fun on ni ib - okęlę, Ile ni ogun na, o fę lọ yawo ra ile ębi.

Awọn ologbe ęgbọn rę ko gbe ile na ta ni doogo na ti şe baa nilę o. Şugbọn awọn aburo rę ti ku mọ ọ lọwọ, nwọn ni awọn ko ję taa. Nwọn ni eruwọ (eewọ) ni, nwọn ni bi awọn ęgbọn rę ba ti tan, bawo ni on yio ti şe ba a ? Oju doog alabosi si pọn bi lesę ina E ko wa ri pe, doogo bilisi mbę. Oluwa rere, jọwọ, gba wa lọwọ doogo alabosi.

Printed and Published by Modupę Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 24/7/64.